Ẹni ti o ba wa ba yin nigba ti ọrọ yin papọ lori arakunrin kan, ti o wa n gbero láti ya yin, tabi lati pin akojọpọ yin, ki ẹ yaa pa a

Lati ọdọ ‘Arfaja – ki Ọlọhun yọnu si i– o sọ pe: Mo gbọ ti ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – n sọ pe: «Ẹni ti o ba wa ba yin nigba ti ọrọ yin papọ lori arakunrin kan, ti o wa n gbero láti ya yin, tabi lati pin akojọpọ yin, ki ẹ yaa pa a».

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – n ṣe alaye wipe dajudaju ti awọn Musulumi ba kojọ lori olori kan, ati akojọpọ kan, lẹyin naa ni ẹni ti o fẹ ba a du ipo aṣẹ wa de, tabi ti o gbero lati pin awọn Musulumi si ijọ ti o pọ ju ẹyọkan lọ, o jẹ dandan fun wọn lati kọ fun un ati lati ba a ja; lati fi ti aburu rẹ danu ati lati fi da aabo bo ẹjẹ awọn Musulumi.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/58223